# IDUPẸ ONIGBAGBỌ́

### Orin Dafidi 107:1-43

### ẸKỌ 47 --- FUN AGBA

**AKỌSORI: "Jẹ ki ohun gbogbo ti o li ẹmi ki o yin OLUWA. Ẹ fi iyìn fun OLUWA" (Orin Dafidi 150:6).**

**I A Gba-ni-niyanju Lati Yin Ọlọrun**

1 Aanu Rẹ̀ beere idupẹ wa, Orin Dafidi 107:1; 103:17; 50:14; Ẹkun Jeremiah 3:22, 23; Deuteronomi 6:7; Titu 3:5-7; Matteu 10:32

2 Ẹ yin In fun ọla nla irapada, Orin Dafidi 107:2-5; 130:7; Luku 2:36-38; 1 Kọrinti 1:30; Heberu 9:12

3 A ni lati fi imoore wa hàn fun igbala kuro ninu wahala, Orin Dafidi 107:6; 50:15; 2 Kronika 20:20-22; Daniẹli 3:27; 6:22; 2 Timoteu 4:18

4 Oun ni Aṣiwaju wa nla, Orin Dafidi 107:7; 77:20; 1 Samuẹli 2:9; Luku 24:50

5 A ni lati yin Ọlọrun, nitori ti O ṣeun, Orin Dafidi 107:8, 9; 92:1, 2; Romu 8:28; Iṣe Awọn Apọsteli 10:38

**II Apẹẹrẹ Ijolootọ Ọlọrun**

1 Aanu Rẹ̀ tilẹ kan awọn ọlọtẹ̀, Orin Dafidi 107:10-16; Nehemiah 9:16, 17, 26, 27

2 Awọn olurekọja, ti o fa ipọnju ba ara wọn, ri oju rere Rẹ̀ pẹlu, Orin Dafidi 107:17-22; Owe 13:15; Mika 7:18

3 O n ṣakoso iṣẹ ọwọ Rẹ̀, O si n sọ iji di didakẹ rọ́rọ́, Orin Dafidi 107:23-32; Owe 30:4; Matteu 8:27; Marku 4:39

4 Iwa buburu ọmọ eniyan sọ ilẹ eleso di aṣalẹ, Orin Dafidi 107:33, 34

5 Aanu Ọlọrun sọ aginju di ilẹ eleso, Orin Dafidi 107:35-38; Isaiah 35:1, 2; 51:3

**III Ibalo Rẹ̀ pẹlu Eniyan**

1 Oniruuru ọna ni O fi n ba eniyan sọ̀rọ, Orin Dafidi 107:39; 94:12; Owe 3:11, 12

2 Oluwa ki i ṣe ojuṣaju eniyan, Orin Dafidi 107:40; Iṣe Awọn Apọsteli 10:34; Efesu 6:9

3 O fẹran awọn talaka ṣugbọn o pa ẹlẹṣẹ lẹnu mọ́, Orin Dafidi 107:41, 42; Jakọbu 2:5; Jobu 5:16

4 Ṣiṣakiyesi nnkan ti Ọlọrun maa n fun ni ni òye iṣeun-ifẹ Rẹ̀, Orin Dafidi 107:43; Daniẹli 12:10; Jeremiah 9:23, 24; Johannu 8:31, 32

### ALAYE

Ọrọ Mimọ́ Ọlọrun kun fun imọran daradara. O n kọ́ ni bi a ti ṣe le lo ayé ẹni, oun si ni amọna wa si ile Ọrun. O ṣe danindanin lati gba **gbogbo** Ọrọ Ọlọrun gbọ́ ki a si gba a sinu ọkàn wa, ki a má si fi apa kan silẹ ninu Iwe Mimọ́. Ninu Ifihan 22:18, 19 a sọ fun ni kedere pe gbogbo Ọrọ Ọlọrun ni o ṣe danindanin ti o si tó lati mu wa wọ inu Ogo.

Eyi ni a ṣe sọ fun ni ninu Psalmu yii pe ki a fi ọpẹ fun Oluwa, ki a yin In ki a si juba Rẹ̀. Iyin si Ọlọrun jẹ ọ̀kan ninu awọn eso ti iriri tootọ ninu Oluwa. Bi a ba wà lara Ajara Tootọ, a o ni eso Ajara Tootọ. Bi iriri wa ba jẹ eke tabi bi a ba ti jafara pẹlu rẹ̀ ti a si ti ṣubu sinu ipo ifasẹyin, iyin wa ko ti inu ọkàn wá: kiki idẹ ti n dun tabi kimbali olohun gooro ni. Bi ayọ Oluwa kò ba jẹ agbara wa, Ẹmi Rẹ̀ kò ni si ninu ọ̀rọ ẹri wa. Iyin awọn eniyan mimọ́ lori ilẹ nihin ti kun fun imisi ati agbara igbeniro to fun ọkàn eniyan, ju bẹẹ lọ o ti dùn to leti Oluwa. Bi a ba n fẹ maa kọrin ki a si sìn niwaju Itẹ̀ Ọlọrun titi gbogbo igba ayeraye, o yẹ ki a bẹrẹ si i ṣe e lati ihin lọ nisisiyii.

Ayọ̀ ti o jinlẹ wà ninu igbala. Dafidi mọ eyi, o si jẹ oloootọ lati jẹwọ pe oun ti sọ iriri oun nù, ati lati gbadura fun imupadabọ rẹ. O wi pe (Orin Dafidi 51:12), "Mu ayọ̀ igbala rẹ pada tọ̀ mi wá." Itanjẹ eṣu kan wa ti o mu ki awọn eniyan gbagbọ́ pe ninu ẹ̀ṣẹ nikan ni a ti le ni ayọ̀ ati inu didun. Dafidi ti ni ayọ yii nigba kan – o sọ ọ nù – o si bá ara rẹ̀ lọwọ Satani, pẹlu ibanujẹ ati aròdun. O mọ iyatọ laaarin èso ẹ̀ṣẹ ati alaafia Ọlọrun. Psalmu kin-in-ni sọ ẹni ti i ṣe ẹni ibukun fun ni. Nigba ti a ba ni isopọ pẹlu Kristi, ti Ẹjẹ Rẹ̀ si wà lara òpó ilẹkun ati atẹrigba ọkàn wa, yoo jẹ ayọ̀ wa lati ṣe ifẹ Rẹ̀ ninu ohun gbogbo, a o fi imoore wa hàn fun idande iyanu kuro ninu akoso ọ̀ta nì, ati fun ominira igbala.

Yoo gbà wa ju iṣẹju diẹ lati le ranti awọn ibukun Ọlọrun ti o ya ni lẹnu. O ti jẹ ohun ribiribi lati maa sin Ọlọrun fun ọpọlọpọ ọdun -- ṣugbọn a ha mọ rírì ọpọ ibukun ti O n da lu wa ni iṣẹju gbogbo? Sa duro ki o si ronu wò. Dajudaju o yẹ ki a "fi ọpẹ fun OLUWA, nitori ti o ṣeun."

Nigba pupọ bi a ba n beerè nnkan lọwọ Ọlọrun, ti a n bẹ̀bẹ niwaju itẹ, yoo dara bi a ba ranti imọran Rẹ̀ pe ki a yin In.

Psalmu kẹtandinlaadọfa (107) yii kún fun eredi ti a fi ni lati yin Oluwa.  O n kó awọn eniyan Rẹ̀ jọ, O n fi Ounjẹ Ọrun bọ́ wọn, O n yọ wọn kuro ninu ìṣẹ́ wọn, O n tọ́ wọn nipa ọna otitọ, O tilẹ ṣaanu fun afasẹyin ti o ti ṣina kuro ti o si taji ninu wahala ati ipọnju.  Ninu ẹsẹ kẹsan a kà pe, “Nitori ti o tẹ́ ifẹ ọkàn lọrun, o si fi ire kún ọkan ti ebi npa.”  Ọlọrun fẹran ọkan ti ebi n pa, ibukun si wà fun ẹni ti o ba tọ Ọ wá pẹlu iru ọkan bẹẹ (Luku 1:53).  Ki i ṣe pe O dá igbi duro nikan, ṣugbọn nigba ti O ba wọ inu ọkàn kan wá, Oun a mu ki igbi riru ti ẹ̀ṣẹ ati arò pa rọ́rọ́.  “Nigba na ni nwọn yọ̀, nitoriti ara wọn balẹ.”

Ko si akoko ti o dara ju lati yin Oluwa ju igba isisiyii lọ.  Nigba gbogbo ni ẹmi isin ati ọpẹ maa n goke lati inu ọkàn eniyan mimọ́ Ọlọrun, ṣugbọn o dara lati sọ ohun ti o wà ninu ọkàn jade.  Ọlọrun fẹran iyin, Oun yoo si bu ọlá fun ẹni ti o ba gbé Orukọ Mimọ́ Rẹ̀ ga lọna bayii.  A n ri ifarahàn aabo iyẹ Rẹ̀ ati ojiji apa ayeraye Rẹ̀ ninu igbesi-ayé wa ojoojumọ, a si n wi pẹlu Onipsalmu pe, “Ẹ fi ọpẹ fun OLUWA; ẹ pè orukọ rẹ̀: ẹ fi iṣẹ rẹ̀ hàn ninu awọn enia.  Ẹ kọrin si i, ẹ kọ orin mimọ́ si i: ẹ ma sọ̀rọ iṣẹ iyanu rẹ̀ gbogbo” (Orin Dafidi 105:1, 2).

**AWỌN   IBEERE**

1 Ki ni iyanju ti Orin Dafidi 107 n gba ni?

2 Njẹ igbesi-ayé awọn ti a ràpada fi iru ẹmi bayii hàn?

3 Awọn ileri iyanu wa ninu Psalmu yii.  Darukọ wọn.

4 Ki ni abayọrisi ṣiṣọtẹ si Ọrọ Ọlorun?

5 Ṣe alaye ohun ti eniyan ni lati ṣe bi o ba bọ́ sinu wahala.

6 Ki ni a reti pe yoo jẹ ère ṣiṣe bẹẹ?

7 Ki ni a kọ́ sinu Psalmu yii nipa jijẹri ninu ile-isin?

8 Ki ni awọn ẹni-irapada ni Ọrun yoo maa ṣe titi ayeraye?

9 Njẹ ojuṣe wa ni lati maa yin Ọlọrun?